

...an okeyi ni igbati Odugbona Oyo, Faniyi nfi ase onję yanlę ...wo Adeoye, Akintola Aşeda pęlu Oloye Anigbami ti ... Ifa mu ki nwon to bęręsi jase



...woran oke yi ni ti Babasango nibiti o ti ngbaladun oti ibilę ati-...lę nibiti Oluwo Adeoye Akanji Ogun ti nba awon çmęwa rę ... ninu Igbo Agidan

# Ęgbę 'ZIKIST' şe ayęwo işę Akintola

ĘGBĘ Zikist, Alakeko eyiti işe okan ninu omo ogun egbe Alakuko ti yan igbimo enia męfa ati ma ba işe lo lori awon isele oşelu ti nsele ni Ipinle Iwo Orun Naijiria nisisiyi.

Ni ibi ipade-ikoko kan ti nwon şe ni Ibadan ni ojo Aje ti işe ojo kędogun osu yi labę baba ęgbę Apapo egbe na, Oloye Adewale Fashanu ni nwon ti şe ipinnu yi.

Awon nkan miran ti o se pataki ti nwon ko jęki enia mo, ni nwon se ninu ipade na.

Gbogbo awon asoju kakiri Ipinlę Iwo-Orun ni o peje si-bi ipade na pelu ti agbegbe Eko.

Asiwaju ęgbę Zikist dupę lowo awon enia ti o wa si ibi ipade na lasiko ti gbogbo ohun ko rogbo ni Ipinlę yi pe "o tilę tun ku awon oloto enia ti o tun nifę si ęgbę Alakuko"

Egbę na fesun kan Ijoba Ipinlę yi pe awon ni nwon nda ruduradu silę nisisiyi. O si kesi gbogbo alatilehin ęgbę Zikist lati mura silę fun "işę aşekara nigbakigba ti asiwaju won ba kesi won.

Oloye Fashanu lodi si oro awon "isansa" ti nwon nso pe awon fi ęgbę Alakuko silę lati bo sinu ęgbę Akintola nitori-pe ęgbę Alakuko ngbero lati papo pelu ęgbę Afenifere.

Oloye Fashanu ni idi na ję eyiti 'ko fęsę mulę ati eyiti awon ologbon enia ko tilę le faramo" nitoripe Alakuko ko-iti fowo si adehun kan pelu ęgbę Afenifere-gbogbo ohun ti ęgbę na şe ni pe nwon gbero lati papo mo ęgbę Afenifere.

Oloye Fashanu so kedere pe iyato tefetefe lo wa larin asiko Ijoba ęgbe Afenifere ni abe Oloye Awolowo ati ti Ijoba abe Akintola, olotu Ipinle Iwo Orun nisisiyi.

Asiwaju egbe Zikist ni yio wa ninu itan akosile pe Ijoba Oloye Akintola ni o şe ibaje ti o tobi julo si egbe Alakuko ju asiko ti Oloye Awolowo wa nina Akoso Ijoba lo.

Oloye Fashanu ni asiko Oloye Akintola ni atikiri ba Oloye Fani-Kayode ni Ile-Ife ni asiko idibo Igbimo Ibile ni odun 1961 ti Oloye Fani-Koyode fi sa lo si Amerika.

Peni asiko Ijoba Akintola yi na ni aihale okan gbe ba egbe Alakuko eyiti o mu egbe na te waya ojiji si asiwaju egbe na, Dokita Okpara lati pada ninu irin ajo re lori idagbasoke ise Aje si ile okere lati le fi gba awon enia re la.

Oloye Fashanu so pe je iyalenu fun on pe lehin gbogbo asise yi, awon alaimokan, odale tun le so Oloye Akintola di omo olokun loni.

## Igbimo Ibile Akure kuna

ĘGBĘ Akeko Akurę ti Ibadan ati Ife Unifasiti fi ęsun kan Ijoba Ipinlę Iwo Orun ni ojo Isęgun ti işe ojo ketadilogun osu kęta odun yi pe, nwon ko nani agbegbe won nipa aipin ohun idagbasoke fun won.

Nwon tun fi esun kan Ijoba Ipinlę Iwo Orun pe bi awon ti nkigbe si won leti pe ki nwon tu Igbimo Afunniso Akure ka. Sibęsibę nwon ko ko ibi ara si. "Ibi ti igbimo na si nse fun wa poju ire lo."

Siwaju si i, nwon so pe, owo ti o şe si Igbimo na lorun ję okę męrin ponun £80,000.

## Aşę Olopa tun de

IPADE ode gbangba ati iwode ni ilu Eko ni ęl pa tun ti fi ofin lu fun osu meji eyiti o bęrę ni ojo kelilelogun osu kęta odun yi.

Ofin na fi aye silę fun Alakoso tabi Oga işę Ijoba lati paşe ipade iwode ati ipade ode gbangba eyiti o ję mo esun, ipade ere, idaraya pelu awon işele miran eyiti ko ni mu darudapo bę silę.


## Fun ere (Kidney) re ni okun

MA A GBADUN BI OMODE KI O SI DABI OMODE. [illegible] CYSTEX [illegible]

## Jęki owo rę ma dagba si larin ikore kan si ekeji ninu ile Ipamo Owo ti Barclays

Nigbati o ba ta eso oko rę fi owo ti o pa si Ile Ipamo owo. Fi sabę abo nitori igbati o ba nfę owo lati fi ra ohun ti iwo o gbin sinu oko, ogun ilędu tabi irinję. Nigbati owo rę ba si wà ninu ile ipamo owo ere a ma ti inu rę jade ni igba de' gbà.



Į FI OWO YI! PAMO SHIĘ?

Barclays Bank ti şe opolopo awon ... ti a ti mo ... panı, boya ę ti ri won tęlę. ... itan nipa awon agbę męta ti won ko eso oko won lori ęja. ... won pa owo pupo.



Okan ninu agbę awonyi si nkorin lo sile to nk'igbe ki gbogbo enia le mo wipe o ti di olowo. Awon orę rę si nya owo lowo rę, iyawo rę ko ri ohunkohun gbà rara. Agbę keji fi owo tirę pamo si abę ibusun, ... ole kan ji dię lo ninu rę ni alę, ... tun ję iyoku.

Agbę kęta logbon ju won lo.

Gbogbo owo rę lo ko lo fi ... sile Ipamo Owo rę Barclays, ki o ba le ra ohun toba fę lati gbin sinu oko ni akoko ati irinję pelu.

Ranti wipe, owo rę wà labę abo ninu Barclays Bank.

BARCLAYS BANK D.C.O.

*Ela lęę won mbę kakiri ni arilę ede yi.*

